# IROHIN IMOLE

*IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA*

No 1,427 THURSDAY AUGUST 12, 1965 (2D)


## Adamodi Olopa Kan W'ewon Odun Meta

OYO:- Ni ejo ojo Bo ti ise ojo karun osu yi ni odomomokunrin kan Sunday Omotosho ti o pe ara re ni Olopa bu s'ekun nigbati Adajo ile ejo giga ti Ijoba ibile Oyo pase pe ki o yara lo fi ewon odun meta jura lori esun pe ademodi olopa na lo jale ati pe o fi ona jibiti ngba owo kakiri pe Olopa ni on ise.

Ninu oro Olopa to ba Odaran na sejo ni o ti se alaye pe ninu odun yi ni Sunday lo si Ijio, Okeho ti o npe ara re ni Olopa ti o gba owo lowo Okunrin Direba kan ti nje Alimi Olalere.

Olopa na tun se alaye pe ni ibikanna ni Sunday tun ti ji owo Ogbeni Alimi Olalere eyiti iye owo na je sile mewa (10/-)

Ogbeni Olalere tun se alaya fun ile ejo pe ni ojo ti odaran yi wa ba on ti o pe ara re ni olopa, o ni nse ton da moto on duro si ibudo awon moto ni Okeho.

Ogbeni Alimi Olalere tun se alaye pe bi on ti de ro l'egbe moto on ni Odaran adamodi Olopa na wa bere lowo on pe ki on mu iwe eri ti on fi nwa moto wa ati pe ti on ko ba ri iwe eri (Licence) on mu wa pe on yio gbe oro na de ile ejo. Olalere tun se alaye pe odaran na tun so fun on pe ki on mu ponun marun (£5) wa.

WO OJU EWE KEFA

## Oloye Ogunsanya So Pe:

# KOSI EGBE DEMO L'EKO

EKO: Ninu irohin kan to jade lati enu Oloye Adeniran Ogunsanya Minista Alam juto eto ile gbigbe ati Alaga Igbimo Amusese fun egbe Alakuko ti ilu Eko ni o ti se alaye pe awon enia kan si ko ara won jo ni ilu Eko lati ma a tan olori egbe Demo to wa ni Ibadan je pe egbe Demo ti de ilu Eko eyiti Oloye Ogunsanya tun se alaye le lori pe ogbon ni awon enia na nda lati le ma tan olori egbe na je ni nwon nse eleyi fun.

Oloye Ogunsanya tun se alaye pe ki i se ona ti awon enia yi ngba tan olori egbe Demo je nipa pe ki nwon maa paro sinu iwe irohin pe awon egbe Demo wa ni ilu Eko bikose wipe ki nwon fi ona eto ibo mo boya egbe Demo ni awon alatilehin ni ilu Eko tabi ko si.

Oloye Adeniran Ogunsanya soro le irohin kan to jade ninu awon iwe irohin meji kan ni ilu Eko sugbon ki ise Irohin Imole eyiti irohin na se alaye pe awon omo egbe Alakuko ti fi ara mo egbe Demo ati pe awon omo egbe Alakuko na to odunrun enia (300).

Oloye na tun kesi awon Olori egbe Demo pe ki nwon to mo pe ko si egbe Demo tabi enia ti nse egbe Demo ni ilu Eko o ni on gba won ni iyanju lati gbe apoti ibo sile ni gbogbo ijoko mejilelogoji to wa ni ilu Eko ti nwon yio ti dibo ninu idibo si ile Igbimo asofin ti Ijoba ibile ilu Eko.

Oloye Ogunsanya tun se alaye siwaju sii pe iro patapata ni awon enia to ko ara won jo lati lo paro pe awon omo egbe Alakuko ti nwon to odunrun ti o wa ni Iha Ariwa ilu Eko ti kuro ninu egbe na lo si egbe Demo (NNDP) o ni irohin to jade ninu awon iwe Irohin meji na ni ki ise otito

Oloye Ogunsanya tun gba awon omo egbe Demo to gbe iru irohin bayi jade lati ko oruko awon omo egbe Alakuko ti won so pe nwon ti kuro ninu egbe na sinu iwe irohin ki gbogbo aiye ri ka ki a le mo pe otito ni awon omo egbe na faramo egbe Demo

Ninu irohin kan to tun de owo wa lati owo egbe Alakuko ti ilu Eko tun fi ye wa pe Irohin to jade ninu awon iwe irohin na e ise owo Oloye T.O.S Benson ati awon elegbe re lati le ma pa iro fun awon elegbe won ni Ibadan pe awon ni enia lehin ni Eko

Awon omo egbe [illegible] tun se alaye pe [illegible] je ohunti o ye ki Oloye Benson ati awon elegbe re fi se a[illegible] gbon lori ohunti o sele si egbe Demo ni Ipinle Iwo-Orun Na ijiria nibiti egbe Demo ti pin si ona meria ni ipinle na ti ede aiyede si tun wa larin won bayi.

Ninu irohin to tun de lati owo Akowe eto Irohin egbe Alakuko fun ilu Eko Oloye F. U Anyiam tun se alaye pe awon enia ti oruko won jade ninu iwe irohin pe nwon ti kuro ninu egbe Alakuko ni o se alaye pe awon enia na ni egbe Alakuko ti yo kuro ninu egbe Alakuko.

Oloye Anyiam tun se alaye pe ko se ise fun awon ti nwon ti yo kuro ninu egbe Alakuko ki nwon tun so pe nwon ti kuro ninu egbe ti nwon ko si ninu egbe na mo.

Oloye F. U. Anyiam tun se alaye pe eleyi je ohuuti o ya enia lenu lati gbo pe o le gba iru awon enia bayi ni odidi osu mejo ki iru awon enia ti nwon so pe nwon kuro ninu egbe ki nwon to so pe awon kuro ninu egbe Alakuko lati lo parapo mo egbe Demo.

Oloye F. U Anyiam tun se alaye pe ohunti o mu Oloye Benson ma se iru eyi ni ona ti o nwa ninu egbe Demo lati le wa gegebi Olori egbe Demo o ni ohunti o fa ti Oloye na fi so ohunti o sele ni nyen.

Oloye Anyiam tun se alaye pe ko si iwe kankan ti Igbimo Amusese egbe Alakuko ti ilu Eko ri gba lati owo awon enia ti nwon se alaye pe nwon to odunrun enia ti o binu fi egbe sile

Wo Oju Ewe Kefa

## KONDO OLOPA L'ARA AWON OSISE



Wo Oju Ewe Kefa Fun Irohin

# IJỌBA ISRAELI KỌ ILE IṢẸ ẸKỌ IWOSAN

**JERUSALEM:—** Irohin ko to afojuba ni ayẹyẹ ti awọn ṣe nipa ṣi ṣi ile ẹkọ iwosan ti Ijọba Israeli kọ si ilu Jerusalem ti iṣe Olu ilu Israeli ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kerin oṣu ti o kọja lọ yi.

Irohin ile iṣẹ Aṣoju Ijọba Israeli ni Naijiria fi ye wa wipe, lati igbati Ijọba ti fe ṣi ile iṣẹ ẹkọ Iwosan na ti ku bi ọjọ meriola ni nwọn ti fi iwe ipe ranṣẹ si gbogbo awọn enia orilẹ ede gbogbo lati wa ba awọn ṣi ile ẹkọṣẹ na.

Ṣugbọn nigbati yio fi di nkan bi ọjọ meria ti nwọn yio ṣe iṣile ẹkọ iwosan na ni awọn enia jankanjankan ti Ijọba fi iwe ipe ranṣẹ si ti bẹrẹsi de si Jerusalem ti iṣe Olu ilu na.

Irohin na tun ṣe afikun wipe, gbogbo awọn Alakoso Ijọba ti nwọn fi iwe ipe ranṣẹ si ti nwọn ko le wa ni nwọn ran awọn Aṣoju wọn wa sinu ilu na.

Nigbati o si di ọjọ ti nwọn yio ṣi ile ẹkọ Iwosan na, ni deede agogo meji ọsan ni gbogbo awọn enia na ti de siwaju ile ẹkọ Iwosan na ti ẹsẹ gbogbo wọn si pe samusanmu.

Bakanna ẹwẹ, ni ẹsẹ gbogbo awọn Minista ati Aṣoju Ijọba Orilẹ ede ilẹ Israeli ti pe ṣamuṣamu ti awọn na si ti mura silẹ, awọn adajọ awọn Dokita, awọn Agbẹjoro ati gbogbo awọn ọmọ ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Orilẹ ede Israel.

Ẹniti o ṣe eto ṣiṣi ile ẹkọ Iwosan na ni Alakoso Ijọba Ilẹ Israeli Ọlọla Levi Eshkol ti o duro ninu aṣọ Oye nla ilu na loju gbogbo awọn alataṣeyẹ ọjọ



**Ọlola Levi Eshkol**
Alakoso Ijọba Ilẹ Israel

## Alabaṣẹyẹ

Ninu awọn enia saraki-saraki ti nwọn wa sibi ayẹyẹ eto iṣile na ti nwọn ṣe ni ọjọ na ni Dọkita Mergesha ẹniti iṣe Minista Alamojuto eto ẹkọ fun Orilẹ-ede Ethiopia ẹniti o wa ninu ilu na nigbati nwọn fi nṣe eto iṣile na.

Ninu awọn enia jankan-jankan ti nwọn tun sọrọ ri ọjọ na ni Ọlọla Eliahu Elath Olori ile ẹkọ nla Unifasiti Heberu. Ninu ọrọ rẹ, Ọlọla na fi ye gbogbo awọn enia ti nwọn wa sibi ayẹyẹ iṣile ọjọ na wipe, awọn Dọkita ti nwọn ṣe wahala lọpọlọpọ lati ẹhin wa tabi ṣaaju asiko yi nipa kikọ awọn ọrọ ile ẹkọ nla na ni iṣẹ Dọkita ati iṣẹ iwosan yio a gbogbo Orilẹ-ede na.

Ọlọla Elath tun sọ ninu ọrọ rẹ wipe, ohunti Ijọba Israeli kọ ile ẹkọ Iwosan na fun ni lati maa kọ awọn ọmọ inu ilu na ni iṣẹ Dọkita ki awọn ọmọ inu ilu na maṣe tun maa lọ si ilẹ okere mọ lati maa lọ kọ iṣẹ iṣegun, ki nwọn si tun le maa tọju awọn alaisan ninu ilu na.

O tun wa ṣe alaye wipe ki iṣẹ ọmọ ilẹ Israeli nikan ni awọn yio maa kọ ni iṣẹ Dọkita, nwọn yio tun maa kọ awọn ọmọ ilẹ okere ni iṣẹ Dokita ninu ile ẹkọ iwosan Unifasiti na.

Ọlọ'a na tun sọ fun gbogbo enia pe ile ẹkọ iwasan ti awọn ti ni tẹlẹ, fun gbogbo awọn ọmọ ilu na ni awọn ti ni wọn fun, ṣugbọn lati inu ọdun 1961 ni Ijọba ti paṣẹ wipe gbogbo ọmọ ilẹ okere ni ki Ijọba maa gba si Unifasiti na ki nwọn maṣe gba ọmọ ilẹ Israeli ni kan mọ.

Irohin na tun ṣe alaye wipe, "Awosifiila sọru" ni ile ẹkọ Iwosan na nitoripe, ile pẹtẹsi alagbeka mokanla ni nwon kọ ile pẹtesi na fun awon omo ilẹ ẹko nla ti nwọn wa nko ẹko ninu ilu na nisisiyi.

## INAWO

Irohin ile iṣe Aṣoju Ijọba Israeli ni Naijiria fi ye wa wipe, Adọrin dinlegbẹta ọkẹ ponun (£11,000,000) ni Ijoba fi kọ ile ẹko Iwosan na ki o to le pari.

Ọtadinlegbẹta iyara ati ibusan (540) ni ile ẹkọ Iwosan na si, lẹhin na ni nwon tun yo ibikan si oto fun awon akẹko lati maa ko won ni iṣẹ Dokita, lẹhin na ni nwon tun ni ibikan ti nwon gbe nko awon kan ni ẹkọ bi atiṣe ntun awon ẹhin ti nwon ba bajẹ ṣe ti nwon yio si tun dara tabi ti nwon yio tun fi wa bi nwon ti ṣe wa tẹlẹ ri.

Lẹhin na ni Ijoba yọ ibikan si oto ninu ile ẹko iwosan na lati maa ko awon omo na ni iṣe itoju awon abiyamọ, iṣẹ bi nwon yio ti ṣe maa po oogun ti Ijoba yio maa lo fun awon alaisan.

Irohin na tun fi ye wa wipe, Ijoba tun nko ile iwosan miran lowo bayi ati Unifasiti nla miran eyiti nwon yio ko pari ni aipẹ yi. Nigbati nwon ba ṣi ko ẹ ẹko na tan ogorin (80) awon Dokita ni nwon yio maa ko jade ninu ile ẹko Unifasiti nla na ni odọdun.

Irohin fi ye wa wipe ọdun meje ni awọn ọmọ ile ẹkọ nla na yio maa fi kọ iṣẹ Dokita ki nwọn to le gba oye ninu imọ ijinlẹ ẹko Dokita ati pe Ẹdẹgbẹta (500) enia ni nwon yio maa gba sinu ile ẹko Iwosan na ni odun kan.

Enia mẹtaleladorin ni nwon ti ṣe idanwo sinu ile ẹko na lati ilẹ Afrika, eyini ilẹ enia dudu ti nwon si ti yege ninu idanwo ti nwon ṣe na, awon omo na yio si ba awon omo ile ẹko na bẹrẹ iṣẹ ninu oṣu kewa odun yi, nigbati ile ẹko na ba bẹrẹ iṣẹ. Ọdun meje ni nwon yio fi ko iṣẹ won.


## Bọ Lọwọ Ọṣọ Ati Ajẹ

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- mejila £2
Iwe Ilana Ifa Iyanrin tirẹ ati etutu rẹ pẹlu Iwosan 20/- mejila £2 5/-
Iwe Egbogi Awogba Arun meji 40/-
Turari iṣẹgun Ajẹ Oṣo ati awọn abinijẹ O wa fun itaja pẹlu alakara Pangolo 10/- Pakẹti 2/- Ki iṣe ti ẹnu fifọn bi ọra ninu awọn ọjọ yi aabo ti o nipọn ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ.

Fi owo ranṣẹ si

J O SHOYINKA
5 Alaba, Street
Odu abọrẹ Mushin

# Iwe si Olotu Irohin Imole

## Ẹgbẹ Oṣewe Nko?

Ẹ ye Olotu ẹ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyin mọmọ ti njade lojojumọ ti fi ọjọ Isimi lati kesi awọn ti nkọ iwe tita ni ede Yoruba ki nwọn ma sun gbagbe ki awọn na fi ẹsẹ rẹ lọlẹ ni asiko nitoripe ewu nbẹ ni apati ọjọ.

Ọgbeni J. O. Shoyinka ṣe wahala titi ki nwọn le da silẹ lọdun ti o koja nwọn fi ipade si ile ẹkọ ti awọn ijọ Eleto (M.B.H.S. Broad Street) ni opopo ọna to fẹrẹ ni Eko nwọn kori ẹnikan rara.

Lati igbana ao gbọ nlo nbọ mọ mo bẹ awọn bi Ẹrukobodo, Yẹyẹ natu, Ọlabitan, Tunji Adeọsun olotu Irohin Imọlẹ, J.O. Shoyinka ati awọn enia jankan - jankan to ku, ki nwọn ma jeki o rẹ wọn.

Laipẹ yi ni nwọn da awọn akọwe tita ti ede Oyinbo silẹ Mo fẹ ki ẹ fi ti won ṣe apẹrẹ ki ẹ ma jẹ ki o pẹ ki ẹ to da ẹgbẹ ra silẹ Ọlọrun ko ni jẹki o rẹ nyin o amin.

Iwaju ni ọpẹ ebiti nyin yio ma re si o Olotu.

Emi ni
L. A. Ayangade
EBUTE-MẸTTA

## A NFẸ ILE-IṢẸ

Olotu, ẹ dakun ẹ gba mi ni aye ranpẹ lati kesi Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun lati ba wa tun ilu wa ṣe ki won fun wa ni ile-iṣẹ ni ilu wa ki awon ọmọ wa na le ma duro nile nwon ko ni ma salo si Ibadan ati Eko mo.

Ilu Iwo ni Ijoba Demo nfi iya jẹ ju, ilu wa ni o gbe ẹgbẹ Dẹmo leri, oba ilu olori egbe Demo ni gbogbo awon asoju wa ni o ba ẹgbẹ Dẹmo lo, Ko wa ye mi to, bi anfa i Ijoba Ẹgbẹ Demo ko ṣe ni fi kan wa ki nwon to tu Ijoba Ipinlẹ Iwo Orun ka ni odun yi.

Ile-iṣẹ nla meji ni Ijoba Ipinlẹ Iwo-Orun gbe si Ogbomosho, ekini ile-iṣe bata kekan ekeji ile-iṣẹ ago owe, kini ṣe ti nwon ko ko ẹkan wa si Iwo, abi awa ti a nku nitori ẹgbẹ Demo ni o tun yẹ ki iya tun ma jẹ.

Orişirişi ile- iṣẹ ni o wa ni Oşhogbo. kini, ilu to ri ile iṣẹ fi ṣe ori tl Iwọ ko fi ṣe ori, to ba jẹ pe, ibo wa ni ẹ nfẹ ki ẹ ma wipe, ẹo tun wọle ninu ilu Iwo mọ. Ẹ ma mu wa ni ọbọ mọ, ni gbati a nṣe ẹgbẹ Afẹnifẹre ni a ni ero- omi ina maramana, Fomu (telephone)oju ọna wa, ni ẹda ati ile ifi we ranṣẹ ki ẹ tete wa ọ lan ṣe ki asiko to re k jẹ.

Emi ni
J, O, A ao
IWO

## Ilu Ilala Nfẹ Atunṣe

Olotu, Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye ninu iwe nyin to kun fun ọgbọn ati o ye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Ariwa Naijiria lori ilu wa ti işe Ilala eyiti o je wipe o to ọjọ mẹta bayi ti a ti nkesi awọn Alaşẹ Ijọba ipinlẹ Ariwa lati ba wa mo oju to Ilu na.

Şugbọn a ko gbọ nkan kan mọ nipa ohunti o şelẹ si ilu wa nipa oju ọna ilu wa nfe ni ile Iwosan titun eyiti nwon ma yio ngbe awọn alaisan lọ,

Ọpọlọpo awọn enia ti aisan diẹ ma ma nyọ lẹnu to ri ku nigbati nwọn ku ti itoju ti nwon si ku iko ojiji inu awa enia ilu na yio pupọ bi Ijoba Ipinlẹ Ariwa ba le tete şe ohunti abi bere yi fun wa o Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi

Emi
Abu Ọmọtọshọ
ILALA

## Ilu Oşoşa Nfẹ Atunşe

Olotu. ẹ dakun ẹgba ni laye diẹ ninu iwe nyin ti o njade lojojumọ lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun papa Oloye Samuel Ladoke Akitola Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun ti o tun jẹ olori ẹgbẹ Dẹmọ lati bawa tun ilu wa şe gẹgẹbi nwọn ti ntun ilu oku şe ni ipinlẹ Iwọ Orun

Awọn nkan ti ojẹ wa lọiya to pọ ju ni ilu wa a nfẹ ero omi ti ao ma mu nigba ti ẹrun ba de wahala ti an şe pọ ki a to ma ri ẹmi mu ni asiko ẹrun.

A tun nfẹ ile iwosan ti a o ma gbe awon alaisan lọ nigbati ara wọn ko ba ya nitoripe awọn ologun enia dudu ko mọ bi ati lo ogun fun alaisan nipa şişe bayi ọpọlọpọ alaisan ni o nku.

Bẹẹa ni ile ẹkọ giga ti awọn ọmọ wa yio ma lọ bi wọn ba ti pari iwe oyinbo mẹfa.

Gẹgẹbi awọn ilu miran ti şe ni ina manamana awa ra nfẹ ina rẹ ni ilu wa.

Ki adẹ ko pẹ lori ki bata lẹsẹ olotu

Emi ni
Jimmy Roy, ỌŞỌŞA

# Kini E duro Fun

Bi o ba ni Aşọ fun fifọ Ati lilọ bi wolen asọ oke, Tafẹta Sapẹti ati orişirişi aşọ ti o ba ni fun fifọ ati lilọ ni işẹju kan.

TETE GBE WA SI ỌDỌ
**JOYCE LUNDRY DYIN & DRY CLEANING SERVICE**
9, Fatiregun St, Brickfield
Apapa Road Ebute Mẹtta

Kia ni ao si fọ ti o ri gba nsẹ !
A le wa gba ni ile rẹ, ki a ko pada fọ bẹ fo tan kọ nomba ile rẹ ranşẹ si wa dan kı Ov e lẹkansẹso ki o si ri bi işẹ wa titi.
Ouo pọọku ni a si

## Iwo Ha Nfẹ le L'Eko Bi ?

| | | |
|---|---|---|
| Room | | £5 |
| Room and Parlour | | £6 |
| Room and Shop | | £15 |
| Shop and Parlour | | £12 |
| Room at | Idumagbo | £5 |
| | Room | £4 10/- |
| | Room | £4 |
| | Room | £5 |
| | Room & Parlour | £11 |
| | Flat | £18 |
| | Flat | £20 |
| | Shop | £3 |

Ti o ba nfẹ okan ninu awon ile wonyi yara tete lo ri Ọgbẹni ODUS:— 187, Bamgboşe Street Lagos.
Nị deede agogo mẹrin irolẹ si agogo mẹfa Irole. Ijafara lewu anfani nla kan ni eyi jẹ fun o pe, o ri ile l'Eko

# EGBOGI JEDIJEDI


CYCLOVEN

Aworan ẹgbẹ yi fi han gbangba ibiti jẹdijẹdi to wa lara rẹ ti nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo Ibẹ ni a npe ni omusu tabi iho idi enia ibiti ẹ ma ngba işe igbọnsẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ikan ninu amodi ti o buru, ni pataki fun okunrin ti o si şoro pupo lati şe iwosan rẹ tan patapata.

Ọpolopo egbogi li owa tia nta kakiri ode isisiyi ti nwọn ma npolowo nwọn fun iwosan rẹ şugbọn boya ni a le ri mẹwa ninu awọn ogun to le şe iwosan arun na daradara.

Awọn elomiran lero wipe boya bi wọn gbe lo si ile iwosan lati lo ge eyiti o ba nyo jade ni omusu on nipa bẹ awọn yio bọ lọwọ rẹ patapata.

Şugbọn awa koro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakanna Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa Ekini ti o bẹrẹ aiko maşe igbọnsẹ deede tabi lojojumọ, gigun kẹkẹ ologere Basikulu pupọ ẹ omiran ẹwu ẹran Suga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba jẹdijẹdi orisirisi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o nyo sode ninu omusu tabi ti o ma nnu ẹjẹ wa lẹhin igbọnşe tabi ti nrin o ninu omusu re ti o ba jẹ bẹ bere egbogi CYCOVEN ti awọn Oyinbo Jamani şeşe wa idi rẹ ki o si dan wo o ri daju wipe iwọ yio bọ lọwọ jẹdijẹdi patapata ti a ta nigboro Naijiria bere ni:-

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Lagos
Phone; 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji

# Ọkunrin Kan Fi Adọjọ Pọnun Tanran "Igbo"

IBADAN:- Ni ile ẹjọ Lekọre ti Ibadan ni Adajọ ile ẹjọ na ti paṣẹ pe ki ọkunrin ọdaran kan Adelabu Adigun ẹni. ọgbọn ọdun ti fi dọjọ pọnun (£150) tanran tabi ki o lọ si ẹwọn ọdun kan ati abọ lori taba Igbo ti awọn ọlọpa ka mọ ọkunrin na lọwọ ni ọjọ ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ karun oṣu yi.

Ninu ọrọ ọlọpa to ba adaran na ṣe ẹjọ fun ile ẹjọ na o ti ṣe alaye pe ni ọjọ karun oṣu yi ni on ka taba igbo mọ ọdaran na (Adelabu) lọwọ ni adugbo Race-Course Ibadan ti o si ko awọn taba igbo na siwaju rẹ.

Ṣugbọn Ọdaran na ko jẹ ki Adajọ ile ẹjọ na bere lọwọ on nigbati o ti fi ye Adajọ ile ẹjọ na pe on jẹbi ẹsun ti ile ẹjọ fi kan on ọdaran na tun ṣe alaye pe on fi taba Igbo na ṣiṣẹ wo ni.

Ninu idajọ Adajọ ile ẹjọ na ni o ti gba Adelabu ni imọran pe yio si dara bi o ba le ma ṣiwo mi ati ju taba igbo to fi nṣowo na eyiti o lodi si ofin Ijọba ati pe ofin na si le pupọ Adajọ ẹjọ na paṣẹ pe ki ọdaran na lọ fi adọjọ Pọnun (150) tanran tabi ki o lọ si ẹwọn ọdun kan ati abọ lafaraba.

## ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

AQUARIUS (Jan22-Feb20) Ẹnia ko ni pọ nibi ayọ isọdi ominira ti o fẹ se nipa bẹ ki o ṣọ ọrọ ẹnu rẹ ki o si ma ṣe akiyesi ọrọ ti yio ma jade lẹnu rẹ.

PISCES (Feb21-Mar20) Irẹpọ yio wa larin iwọ pẹlu ẹnikẹni ti o ba mba lo pọ ma ṣakiyesi ọrọ ẹnu rẹ ki o si ma ṣo iwa hu bi o ba nfẹ ki gbogbo enia fẹran rẹ.

ARIES (Mar21-April20) O san fun ọ ki o gba afẹgun lọ sibọran ju ki o wa ni oju kan na lọ paro ohunti o njẹ bi bẹko am di inu yio ba ọ ja.

TAURUS (April21-May20) Iwa ko ni fi enia silẹ iwa rẹ ni yio fi isu en ti iwọ nṣe han Bi o ba tiẹ lọ si irin ajo yio se ọ ni anfani.

GEMINI (May21-June22) Toju owo rẹ nitori ki awọn ọmọ jaguda ma ba fi oju ja ọ ki o maṣe fi eti si ọrọ awọn alaheso irohin eladun kan yio mu inu rẹ dun.

CANCER (Jun22-July22) Bi o ba ri wipe o ṣoro fun ọ die maṣe tiju lati wa iranlọwọ ewo re yio si te ohun ti o fe ohun ayọ yio de si ọ ni aṣale oni.

LEO (July23-Aug22) O fe ghero nkan ayọ si ara re ṣugbọn maṣe ṣe e ni kanju Ire ni gbogbo oju oni yio jẹ fun ọ.

VIRGO (Aug22-Sept23) Jiji ti iwọ yio ji ni owurọ yi ninu ayọ ni iwọ yio jisi, ayọ na yio si ba ọ kale.

LIBRA (Sept24-Oct23) Bi o ba ri ohun kan dẹ ti ko dun n o o mu maṣe ko ibi ara si nse i ki o kuku ṣe tirẹ niya a ọrọ miran.

SCORPIO (Oct24-Nov22) Fi oriti ki o si la oju rẹ si ẹ maṣe jẹki oju ti ọ lati wa iranlọwọ lọ ọdọ ẹlomiran owọ rẹ yio si to ohun ti o fe.

SAGITTARIUS (Nov23-Dec21) Maṣe fura lati fi ohun ti o gba ero ṣe bi o ba se tẹ ọwọ rẹ yio tẹ ohun ti o fẹ maṣe jẹki are mu ọ rara.

CAPRICORN (Dec22-Jan21) Ọrẹ ni gbogbo awọn ọkunrin yio ma ba ọ ṣe loni bẹni awọn yio ma fẹ ko o ṣe ọkọ awọn.

GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!! BI INA WỌLE OKUNKUN YIO PARADA IYE ! DAJU




BERE EGBOGI TUNTUN TI WỌN NPE NI :—

"DROSELA"

Mejireṣkesi ni igboro Ilu Eko tabi Nigeria

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu ti iṣẹkẹn bi ọdun kan ti a jubẹ lọ, awọn egbogi robirọbi ti wọn nta kakiri tabi ipolowo ni o iṣirisi ko lese iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ ṣe ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara ilu Faranṣe ti nwọn npe ni "DROSLIA" oju'owo hauuhaun atamatase egbogi fun Ikọ ẹgbe Ikọ Aiperi, Ikọ Awugbọn Ikọ Awọn ogun Ikọ ọnfun, Ikọ Ile. Ikọ ti o mọ mu enia tirin ẹbẹ nigba kugb Itiru" Ifun wa (Lungs) tabi ti o ni mu enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan DROSELIA wo Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igba aya ati bi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio sisan patapata iwọ yio si ma jẹun daradara, iwọ yio si sun lọ pẹlu alafia de ṣọ. Bere egbogi yi ati awọn oriṣi fisi, Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:-

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street Lagos
Phone 2287 Nigeria (Ọja Ita Faji)

ATI NI ṢỌBU

IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba.

'UROYSAN DRAGESS'

Fun itọju t bi fifọ Apo Ile Itọ (Kidney Blinder) fun ọkunrin tabi obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu orunkun, Ibadi, Gige tabi riro eri itọ, tabi itọ ji o enia ọ inu tukuru u Pipọn aikoleri itọ to fakuregbe orunkun owo ẹsẹ Eji a wiwu tabi riro.



Ara sisan ritobi atọ ie gbe ra konkọn tabi ki kia didapa ariningbakuaba atio oriṣi awọn aisan tabi modi wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yi wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Mejireṣkesi ni ilu Naijiria nitori na sọra ki awọn eleru tabi awọn oni robirọbi ma ta oriṣi miran fun ọ, maṣe gba rara! Owo rẹ ie Sile mẹfa abọ 6/6d owo Oko sile kan ati abọ. (1/6d.)

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos

**Awon Ilu Ogbagi So Pe:**

# Akoko Wo Ni Ijọba Yio Fun Wọn L'ọba Titun ?

EKO:— Ninu Irohin kan ti o de ilẹ iṣẹ wa lati ọwọ akọwe ẹgbẹ awọn ọmọ ilu Ogbagi ni ẹkun Akoko ti ẹka Eko Ọgbẹni R. O Sanni, ni awọn ọmọ ilu na ti sọ pe lati ọjọ kejidinlogbọn oṣu kẹjọ ọdun 1962 ti Ọba ilu wọn ti ku pe ko si Ọba kankan ti o tun jẹ mọ ri ilu na.

Awọn ọmọ ilu ni tun ṣe alaye ninu irohin wọn pe gẹgẹbi eto iṣẹdalẹ ilu wọn, nwọn ni lẹhi oṣu mẹta ti Ọba na bi ti w'aja ni wọn gbọdọ jẹ Ọba miran.

Nwọn tun ṣe alaye pe a niye igba lo jẹ wipe awon Afọbajẹ ti yan awọn enia mẹta ti nwọn to lati jẹ Ọba ilu na ati pe ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiri si fi aṣẹsi ẹniti o tọ lati jẹ Ọba ilu na

Awọn ọmọ ilu na tun ṣe alaye pe Ijọba ti ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) nṣe akoso rẹ kuna lati yan ẹniti o tọ gẹgebi Ọba ilu Ọlogbagi ti ilu Ogbagi ni ẹkun Akoko.

Awọn ọmọ ilu na tun ṣe alaye pe dipo ki Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun yan ẹniti o tọ si ori oye Ọba na awọn enia kan ṣe ti idile rẹ ko mọ nkankan nipa eto oye ọba Ọlogbagi ilu Ogbagi lo nṣe bi ọba ilu na ti o si nṣe eto nipa ilu Ogbagi ti ko tọ si awọn ọmọ ilu na tun ṣe alaye pe eleyi jẹ ohunti ko ba eto ọna ofi ilọ rara.

Awọn ọmọ ilu na tun ṣe alaye ninu irohin won pe ẹniti o wa lori ipo ọba ilu na ko si si eto anfani kan to ṣe si ilu na gẹgẹbi Ọba tabi pe ohunti o le ṣe ti o le dabi ọba ilu na bikoṣe pe ẹgbe Dẹmọ to nṣe eto akoso lo nhu iwa aito ti o fi jẹki iru ẹniti o wa ni aye Ọba na ma ṣe gẹgẹbi o ti nṣe.

Awọn omo ilu na lokun rin ati lobinrin tun ṣe alaye pe gbogbo ohunti ẹgbẹ Dẹmọ nṣe ni ilu na lo jẹ pe o su wọn patapata ati pe awọn ko si fi ara mọ eto na rara.

Nwọn tun ṣe alaye siwaju si pe awon ohun eto iṣẹdalẹ miran to yẹ ni nwọn ṣe ni ilu na eyiti o jẹ pe Ọba ilu ni o ni tabi ṣe ni nwon fi silẹ ni ilu na ti nwon ko ṣe lati igbati Ọba Ọlogbagi to waja.

Ni ipari awọn ọmọ ilu Ogbagi tun ṣe alaye pe ẹgbẹ Dẹmọ ti nṣe akoso Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti sọ pe awọn ki aṣẹ eto Oye wa lọwọ re ati pe awọn enia ilu Ogbagi ki iṣe enia ti o fẹ ire, alafia ati ilọsiwaju ipinlẹ na ati paapa pe awọn enia ilu si tun jẹ ọta Ijọba ti nṣe akoso ipinlẹ na.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣe alaye pe nitori eyi, gbogbo awọn ọmọ ilu na lọkunrin ati lobinrin ni yio faramọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati pe ki nwọn si tun dibo wọn fun ẹgbẹ na lati le pa ẹgbẹ Dẹmọ run patapata ninu eto idibo si ile igbimọ aṣofin Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria to mbọ yi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun pa ohun wọn pọ pe lagbara Oluwa pe ẹgbẹ Dẹmọ (NNDP) ti o ngbe awọn enia ti ko ni ẹṣẹ si ẹwon aimọwọ ati alaimẹsẹ ti nwọn tun nfi iya jẹ ẹniti ko lẹṣẹ yio kuna patapata ninu idibo si ile Igbimọ aṣofin Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun to mbọ yi.

## Ọdaran Kan Fi Ẹwọn Ọdun Kan Jura

IBADAN:— Ninu ile ẹjọ Ijọba ibilẹ ilu Ibadan ni adajọ ti sọ Ọgbẹni Abraham Fayẹwo ẹni ogoji ọdun si ẹwọn ọdun kan onişẹ aṣekara lori ẹsun ole jija, ti ọdaran na ko si gba pe oun jẹbi ẹsun na ti nwọn fi kan.

Oni irohin wa to wa ninu ile ẹjọ Ibilẹ Ibadan onipo keji sọ fun wa pe, ni ẹjọ Aṣe ti ṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni ọdaran na lọji owo Iyaafin Alice Odubola ni agbegbe ka ti o njẹ Ekotẹdo ni Ibadan ti iye owo na si jẹ pọn un mẹrin larin oṣu kẹta si ẹkẹrin ọdun yi.

Ninu ọrọ awijare Abraham Fayẹwo ni o ti sọ fun adajọ pe, On ko jẹbi ẹsun na irọ ni awọn enia na pa mọ oun.

Ninu idajọ adajọ na ni o ti sọ pe oun gbagbọ pe, oti tọ ni ọdaran na ji owo Iyaafin Alice Odubola, ko si wa si ọrọ kan ti ọdaran na le sọ ti oun yio gba ọrọ ẹnu rẹ gbọ.

Ni adajọ ha ṣe ẹjọ na gẹgẹbi a ti ko soke irohin wa na.


**Ipolowo Oja Rẹ ko Ti Yege**

*Nitoripe*

O KO TI POLOWO QJA

**SINU IWE IROHIN IMOLE**

T'ODUNKA FUN GBOGBO ENIA

KQWE IPOLOWO QJA RẸSI

ADVERTISEMENT MANAGER

**IROHIN IMOLE**

16 Bamgboşe Street, Phone 21935 Lagos



BERE EGBOGI ARỌN

**VERMZYN**

Oluwo egbogi atamatase ti o daju fun iparun awọn "ARỌN" buruku gbogbo lara enia, papa tabi ni pataki fun ARỌN latanlatan tabi arọn kinişa ti o ma mu idiwọ wa fun ẹgbagbeje obinrin lati loyun tabi eti o ma nba oyun jẹ lara Obinrin.




Bi si ni egbogi yi dara fun gbogbo ẹniti aran agbẹdu Igba aya, ọna ọfun, sisi lẹhin bi ake tabi arau oju pẹlu Meji irufọ egbogi arọn yi osi ni gbogbo ilẹ Naijira isẹ rẹ si daju AKIYESI PATAKI

Ri daju wipe o ti re eekọ ọwọ ati ẹsẹrẹ daradara ki oto lo egbogi arọn yi gẹgẹbi awọn Jaman ti o şe ti juwe lilo re Fun agbalagba ikan ni o wa fun. Berre orisirisi egbogi arọn fun ọmọde pẹlu wọn nbẹ fun tita ni şọbu awọn

ADEDUN CHEMIST

14, Wakeman Street, Yaba.

Waterloo Medicine Stores

8, Palmchurch Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORES

4 Tinubu Square, Lagos

